# IJỌBA KRISTI LORI ILẸ̀ AYÉ

## Sẹkariah 6:12, 13; 12:9, 10; 14:4-21

## ẸKỌ 428 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "On ni yio si kọ́ tẹmpili Oluwa; on ni yio si rù ogo, yio si joko yio si jọba lori itẹ rẹ̀; on o si jẹ alufa lori itẹ rẹ̀; imọ alafia yio si wa lãrin awọn mejeji" (Sẹkariah 6:13).**

**I Awọn Asọtẹlẹ Ipadabọ Kristi Lẹẹkeji**

1 Ọrọ ti Joṣua, olori-alufaa sọ, ati igbekalẹ isin ni Jerusalẹmu jẹ asọtẹlẹ nipa Kristi ati Ijọba Rẹ̀ ti o n bọ̀, Sẹkariah 6:12, 13; 3:8, 9

**II Ifihan Kristi**

1 Nigba ti ogun awọn orilẹ-ede bá kọjuja si Jerusalẹmu, awọn Ju yoo kigbe soke fun Messia wọn, Jesu yoo si wá ninu ifarahan Rẹ̀, Sẹkariah 12:9, 10; 14:1-3; Malaki 3:2-6

2 Ifarahan Kristi yoo jẹ lori ọke Olifi, Sẹkariah 14:4; Iṣe Awọn Apọsteli 1:9-12

3 Isẹlẹ nla yoo sẹ̀, Oke Olifi yoo si là si meji, afonifoji nlánlà yoo si wà laaarin rẹ̀, Sẹkariah 14:4, 5

4 Nigba ifarahan Oluwa, awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ yoo si wà pẹlu Rẹ̀, Sẹkariah 14:5; Ifihan 17:14; 19:11-16; Juda 14

5 Nigba ipadabọ Kristi irọkẹkẹ ǹlánlà yoo ṣẹlẹ loju ọrun ati lori ilẹ ayé, Sẹkariah 14:6-8; Orin Dafidi 50:3, 4; Matteu 24:29, 30; Marku 13:24, 25; Ifihan 6:12-17; 16:18-21`

**III Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun Kristi**

1 Kristi yoo jọba lori gbogbo ayé, Sẹkariah 14:9; Orin Dafidi 22:27; Filippi 2:10, 11

2 A o ṣẹgun gbogbo ogun ayé a o si maa gbé Jerusalẹmu lai lewu, Sẹkariah 14:10-15; Jeremiah 23:5, 6; Ifihan 19:11-21

3 Gbogbo orilẹ-ède ni yoo pejọ ni Jerusalẹmu lati sin Oluwa, a o si jẹ orilẹ-ède ti o bá kọ̀ niya, Sẹkariah 14:16-19; 8:20-23; Isaiah 66:23; Mika 4:1, 2; Habakkuku 2:14

4 MIMỌ́ SI OLUWA ni yoo si jẹ́ ami ni gbogbo akoko ogo naa, Sẹkariah 14:20, 21; 1 Tẹssalonika 3:13

### ALAYE

A ko mọ pupọ nipa Wolii Sẹkariah. Ni akoko igbekun Babiloni, Sẹkariah jẹ ọ̀kan ninu awọn ti o pada si Jerusalẹmu fun itunkọ́ Tẹmpili. Awọn Ju ṣe alaini, wọn kò si lagbara ṣugbọn aninilara orilẹ-ède ajeji ti o gba ilẹ wọn lagbara, wọn si le. Nitori idi eyi iwuwo ọkàn ati irẹwẹsi si bẹrẹ si wọ ọkàn awọn Ju wọnni ti o pada si Jerusalẹmu. Nitori naa iṣẹ́ Sẹkariah ni lati mu igbagbọ́ wọn le ninu Ọlọrun, lati rú ifẹ wọn soke ni kikọ́ Tẹmpili ati itungbekalẹ isin Ọlọrun. Nipa bayii o sọ pupọ ninu ileri ologo ti ibi Messia ati awọn asọtẹlẹ kikun ti ipadabọ Messia nigba ifarahan Rẹ̀ ti o wà ninu ọrọ Ọlọrun.

**Ẹka**

A pa a laṣẹ fun Sẹkariah lati mú fadaka ati wura ki o fi ṣe adé pupọ, ki o si gbé wọn ka ori Joṣua, ki o si pe e ni apẹẹrẹ Ẹka. Joṣua ni yoo kọ́ Tẹmpili naa pari, a o si fi jẹ alufaa lori rẹ̀. Ninu Sẹkariah 3:8, 9 a kọ ẹ̀kọ pe OLUWA JEHOFA ni ẸKA naa, Oun ni a o si mú wá ti yoo mú aiṣedeedee ilẹ naa kuro ni ọjọ kan. Gẹgẹ bi a ti gba Joṣua niyanju lati tún Tẹmpili kọ́ ati lati mú isin otitọ pada bọ̀ si Jerusalẹmu bẹẹ gẹgẹ ni Olori Alufaa tootọ, ti i ṣe Jesu Kristi, yoo pada wá ni ọjọ kan sori ilẹ ayé yii lati gbé Ijọba Rẹ̀ kalẹ, yoo ṣakoso, yoo si jọba lori ilẹ ayé.

**A Sọ Asọtẹlẹ Awọn Isẹlẹ Nla**

Ni akoko igbesi-ayé Sẹkariah ati ninu itan iṣẹdalẹ awọn Ọmọ Israẹli, inunibini ati ibanujẹ pupọ ni o ti wà fun awọn aṣayan eniyan Ọlọrun. Ṣugbọn bi Ẹmi Mimọ́ ti mi si Sẹkariah lati kọ iwe, o sọ nipa igba ipọnju kan fun Israẹli eyi ti yoo pọ ju gbogbo eyi ti wọn ti ri lọ. Ni tootọ yoo jẹ́ akoko ti gbogbo ogun aye yoo dojukọ Jerusalẹmu, a o si pa ilu naa run to bẹẹ ti yoo fi jẹ pe idaji awọn ti o wa ni ilu ni yoo ṣẹku. Ṣaaju ki awọn iṣẹlẹ wọnyii to ṣẹ̀, a mọ̀ lati inu awọn asọtẹlẹ miiran pe a o ti gba Iyawo Kristi soke kuro ninu ayé, wọn yoo si maa jẹ igbadun Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Laaarin akoko ibukun ti awọn eniyan mimọ́ yii, Ipọnju Nla yoo gbilẹ kan lori ilẹ ayé. Akoko awọn Keferi yoo ti dopin; ṣugbọn ni akoko ipọnju nla yii, awọn Ju yoo kigbe si Messia wọn.

Ni ibẹrẹ ipọnju naa awọn Ju yoo wà ni irọra nitori wọn yoo bá "ọmọ-alade ti yio wá," ani aṣodisi-kristi dá majẹmu. Ṣugbọn gẹgẹ bi asọtẹlẹ Daniẹli, aṣodisi-kristi yoo da majẹmu naa laaarin igba ipọnju naa (Daniẹli 9:27). Yoo dojukọ awọn Ju, yoo joko ninu Tẹmpili yoo si maa fi ara rẹ̀ hàn bi Ọlọrun (2 Tẹssalonika 2:4).

Gbogbo ayé yoo wà ninu ipọnju nla, iru eyi ti a ko ti i mọ ri, ṣugbọn yoo tilẹ buru jù fun awọn Ju. Awọn Ju yoo ni ibanujẹ, iru eyi ti wọn kò ti i ni ri ni gbogbo itan ibanujẹ iṣẹdalẹ wọn, lootọ ipa meji ninu mẹta ninu awọn Ju ti o wà laaye ni yoo kú (Sẹkariah 13:8). Ni akoko yii ti a n pè ni igba ipọnju Jakọbu, awọn Ju ti o ba ṣẹku yoo kigbe si Oluwa, wọn yoo si gba Kristi ni Messia wọn. "Emi o si tú ẹmi ore-ọfẹ ati ẹbẹ sori ile Dafidi ati sori Jerusalẹmu: nwọn o si ma wò mi ẹniti nwọn ti gún li ọ̀kọ, nwọn o si ma ṣọ̀fọ rẹ̀, gẹgẹ bi enia ti nṣọ̀fọ fun ọmọ ọkunrin rẹ̀ kanṣoṣo" (Sẹkariah 12:10).

Nigba ti wọn ba ri àpá Kalfari ni ọwọ́ Jesu wọn o beere pe, "Ọgbẹ́ kini wọnyi li ọwọ rẹ?" Nigba naa ni yoo dahun pe, "Wọnyi ni a ti ṣá mi ni ile awọn ọrẹ́ mi" (Sẹkariah 13:6). Lati inu ipọnju nlá nlà ni idamẹta awọn Ju ti o ṣẹku yii yoo yipada si Kristi, ti a o si gbà wọ́n là (Romu 11:26, 27). "Emi o si mu apá kẹta na là ãrin iná, emi o si yọ́ wọn bi a ti yọ́ fàdakà, emi o si dán wọn wò, bi a ti idán wura wò: nwọn o si pè orukọ mi, emi o si gbọ́ wọn: emi o wipe, Awọn enia mi ni: awọn o si wipe, OLUWA li Ọlọrun mi: (Sẹkariah 13:9).

**Ifihan**

Nigba ti Jesu Oluwa ba pada bọ̀ si ayé yii nigba Ifarahan, Oun yoo duro lori Oke Olifi, ibi kan naa gan an ti O ti goke re Ọrun; ṣugbọn yoo wá ni akoko yii bi alagbara aṣẹgun Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa. Ifarahan Rẹ̀ yoo mi ayé kijikiji, isẹlẹ yoo sẹ̀, yoo si mu ki Oke Olifi ki o là si meji. Afonifoji nla yoo si wà laaarin rẹ̀; oorùn yoo ṣokunkun, awọn irawọ yoo si já lulẹ (Ifihan 6:12-17). Kristi yoo wá pẹlu awọn ogun Ọrun lori ẹṣin funfun pẹlu Rẹ̀. A o dojuja kọ aṣodisi-kristi nitori Oluwa yoo pa awọn ogun ayé run nipa itanṣan bibọ Rẹ̀, "ẹran-ara wọn yio rù nigbati nwọn duro li ẹsẹ̀ wọn, oju wọn yio si rà ni ihò wọn, ahọn wọn yio si sọkì li ẹnu wọn." Eyi yii ni a n pè ni Ogun buburu ti Armageddoni ninu eyi ti a o pa gbogbo ogun ayé run, ti a o si pe awọn ẹyẹ oju ọrun lati jẹ ẹran-ara wọn (Ifihan 19:14-21). A o ṣẹgun aṣodisi-kristi ati wolii eke, a o si dè e fun ẹgbẹrun ọdun (Ifihan 20:1-3). Ninu ija gbigbona yii, a o ṣẹgun agbara ẹ̀ṣẹ ati okunkun, a o gba Jerusalẹmu là, Kristi yoo si tẹ́ itẹ Ijọba Rẹ̀ yoo si maa jọba pẹlu awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀.

**Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun**

Gbogbo orilẹ-ède ayé ni yoo fẹ alakoso kan ṣoṣo nitori Kristi ni Olori ijọba naa. Awọn eniyan mimọ́ ti o wà pẹlu Rẹ̀ yoo maa ṣakoso labẹ Rẹ̀, awọn kan lori ilu marun-un, awọn miiran lori ilu mẹwaa. Ninu ẹkọ wa, a ka a pe olukuluku ninu awọn orilẹ-ede ti o dojukọ Jerusalẹmu, ti o ba si kù silẹ, yoo maa lọ ni ọdọọdun lati sin Ọba, Oluwa awọn ọmọ-ogun, ati lati pa Ase Agọ mọ́. Ọdọ-Agutan ti Kalfari ni imuṣẹ Ase Irekọja; Ajọ Ọsẹ tabi Ajọ Ikore ni a muṣẹ ni titú ẹmi jade (ni ọjọ Pẹntikọsti), nisisiyii a n wọna fun Ase Agọ ti a o muṣẹ nigba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun. Labẹ Ofin Mose, Ase Agọ ni akoko igba ti awọn eniyan n kọ́ Ofin lati ẹnu olori alufaa. Olori Alufaa Giga wa ti o ti lọ si Ọrun n pada bọ̀ lati tẹ́ Itẹ Ijọba Rẹ̀ ni Jerusalẹmu, lati ibẹ si ni Ofin yoo ti maa ti ẹnu Rẹ̀ jade lọ, gbogbo orilẹ-ede ni yoo si pejọ pọ̀ sọdọ Rẹ̀. "Nitori lati Sioni ni ofin yio ti jade lọ, ati ọ̀rọ OLUWA lati Jerusalẹmu. On o si dajọ lãrin awọn orilẹ-ède, yio si ba ọ̀pọlọpọ enia wi" (Isaiah 2:3, 4).

Rò bi akoko yii yoo ti jẹ́ igba iyanu tó. Bibeli sọ fun wa pe awọn aginju yoo "tanna bi lili": sibẹ ki yoo si ifi onjẹ ṣofo, ṣugbọn olukuluku eniyan ni yoo ni ọpọ onjẹ. Ki yoo si ẹranko ti yoo pa ni lara, nitori "Ikõko ati ọdọ-agutan yio jumọ jẹ pọ, kiniun yio si jẹ koriko bi akọ-malu: erupẹ ni yio jẹ onjẹ ejò. Nwọn ki yio panilara, tabi ki nwọn panirun ni gbogbo oke mimọ́ mi, li OLUWA wi" (Isaiah 65:25).

A o mú ohun iparun kuro lori ilẹ, nitori Ọrọ Oluwa sọ fun wa pe: "Nigbana li oju awọn afọju yio là, eti awọn aditi yio si ṣi. Nigbana li awọn arọ yio fò bi agbọ̀nrin, ati ahọn odi yio kọrin" (Isaiah 35:5, 6). Gbogbo ohun ija ogun ni a o parun. "Nwọn o fi idà wọn rọ ọbẹ-plau, nwọn o si fi ọ̀kọ wọn rọ dojé; orilẹ-ède ki yio gbe idà soke si orilẹ-ède, bẹ̃ni nwọn ki yio kọ́ ogun-jijà mọ́" (Isaiah 2:4). "Emi o si ṣe ariya ni Jerusalẹmu, emi o si yọ̀ ninu awọn enia mi: a ki yio si tun gbọ́ ohùn ẹkún mọ ninu rẹ̀, tabi ohùn igbe" (Isaiah 65:19).

**Mimọ́ Si Oluwa**

Ohun aimọ́ kan ki yoo si ni Jerusalẹmu, yoo si jẹ́ mimọ́ fun Jehofa. Ẹṣin ti a maa n darukọ bi ẹranko ogun ati itajẹsilẹ ni a ki yoo lò fun ogun mọ́ nigba ayé titun naa. Jehofa nikan ni a o maa lò wọn fun a o si kọ orukọ Rẹ̀ sara agogo tabi ṣaworo wọn gẹgẹ bi Ẹni ti O ni wọn. Akọle kan naa yii "MIMỌ́ SI OLUWA" ni o wà lara àwo wura ti o wà niwaju fila olori alufaa (Ẹksodu 28:36-38) lati fi i hàn bi ẹni ti a yà sọtọ fun iṣẹ-isin Jehofa. Awọn ikoko tabi ohun-elo ti a n lò fun awọn iṣẹ-isin miiran gẹgẹ bi ilana iṣẹ-isin alufaa labẹ Ofin ni a o kà yẹ bi ohun mimọ́ ni ayé titun ati bi awo ti a fi n gba ẹjẹ ẹran irubọ. Ni tootọ gbogbo ilẹ naa, ati ohun gbogbo ti o wà ninu rẹ̀ ni yoo jẹ́ mimọ́ fun Oluwa.

**Jijẹ Alabapin**

Ni kika Bibeli wa kò yẹ ki a ro awọn ọrọ inu rẹ̀ bi itan igba ti o ti kọja lọ, tabi ki a maa ro awọn asọtẹlẹ rẹ̀ bi awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ni akoko ti o jinna réré to bẹẹ ti ki yoo fi ṣẹlẹ ni igba ti ayé wa. O ṣe e ṣe ki olukuluku wa jẹ́ alabapin ninu Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun ti Kristi ti o logo yii.

Bawo ni a ṣe le ni idaniloju pe awa yoo ni anfaani lati wà nibẹ, lati jẹ igbadun ibukun ayé yii ti ki yoo si egun, tabi ogun ati irọkẹkẹ ogun, ati lai si ire-ije ogun? Bibeli sọ fun wa pe a gbọdọ foju sọna, a si ni lati mura silẹ fun Ipalarada. Ki a to le wà ni imurasilẹ fun Ipalarada a ni lati jẹ́ aṣẹgun ni kikun, a baa wà láàye lori ilẹ ayé yii, tabi a ti lọ si afonifoji ojiji ikú, ti a si ti sin ara wa sinu ilẹ. Nigba Ipalarada awọn okú ninu Kristi ni yoo kọ jinde, ati awọn ti o wà láàye ti o kù ni a o gbà soke lati pade Oluwa ni awọsanma. Ipalarada yii yoo gbé wa lọ si Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan nibi ti a o ti bọ́ lọwọ ipọnju ti yoo dé sori ilẹ ayé. Lẹyin Ase Alẹ-Igbeyawo Ọdọ-Agutan awa yoo wà lara awọn ti yoo gun ẹṣin funfun ninu ogun Oluwa ti yoo pada wa sori ilẹ ayé yii. Lati wà ni imurasilẹ fun Ipalarada jẹ́ idaniloju pe awa yoo jẹ igbadun gbogbo awọn ibukun ti Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun pẹlu Kristi fun ẹgbẹrun ọdun.

Wo akoko ologo ti o n duro de awọn wọnni ti n fi tifẹtifẹ gba ọna irẹlẹ ti Agbelebu nigba ti wọn wà ninu ayé yii. Ọna irẹlẹ ti a n gbà lati tẹle Jesu ni igbesi-ayé ododo ati mimọ́ yii yoo yọrisi akoko ologo nigba ti awa yoo maa gbé, ti a o si maa jọba pẹlu Rẹ̀. Lẹyin igbadun ibukun wọnyii fun ẹgbẹrun ọdun, Ọlọrun tun ni awọn ibukun ti o ga ju awọn wọnyii fun wa, nitori pe Oun yoo dá Ọrun Titun ati Ayé Titun ti a o maa gbadun titi ayé ailopin. Awọn ipese wọnyii kọja ohun ti a le fi ọkan rò lọ nitori "Oju kò ri, ati eti kò gbọ, ti kò si wọ ọkàn enia lọ, ohun wọnni ti Ọlọrun ti pèse silẹ fun awọn ti o fẹ ẹ."

AWỌN IBEERE

1 Orukọ wo, tabi oyè wo ni a fi fun olori alufaa ti i ṣe apẹẹrẹ Kristi Olori Alufaa wa?

2 Ninu ẹkọ wa, sọ asọtẹlẹ ti o n sọ nipa ijiya Kristi.

3 Iru ipo ti ẹmi wo ni awọn Ju ti o wà láàye ni akoko ipadabọ Jesu yoo wà?

4 Ta ni yoo wá pẹlu Kristi? Tabi Oun nikan ni yoo wá?

5 Sọ awọn iṣẹlẹ nlá nlà ti yoo ṣẹlẹ lori ilẹ ayé ati ninu awọn ogun ayé nigba ti Oluwa ba fara hàn.

6 Ṣe apejuwe Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.

7 Bawo ni a ṣe le ni idaniloju pe awa yoo wà lori ilẹ ayé yii lati jẹ igbadun ibukun Ẹgbẹrun Ọdun?